# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ . .

VOL X' 846 LAGOS SATURDAY NOVEMBER 24 – NOVEMBER 30 1962 KỌBỌ MEJI (2D)


## ORO BEHIN YO !

# Dokit.. Maja Bo Awon Loju Egungun O Ni On Ti Fe Dana Sun Ile Igbimo Tipe

EKO Sangba fọ ni ijẹta ni iwaju adajọ Kotu-ganian Ọgbẹni G Ṣowẹmimọ nigbati ẹlẹri Ijọba Dokita Oladipọ Maja jẹwọ wipe on alara paapa ti gero lati dana sun ile Igbimọ awọn aṣofin Ijọba Apapọse l'Eko tipẹ nitoripe gbogbo iwa ti awọn aṣoju ti nwọn yan sibẹ nhu ko tẹ on lọrun rara. O ni nigbati gbogbo awọn asoju igbimọ na ba wa ni ajọ ipade wọn ni on fẹ dana sun ile na.

Dokita MAJA ti o ti bẹrẹ ẹri ọrọ rẹ ni ọsẹ ti o koja lori ẹjọ ọtẹ ti ọlọpa mba Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori egbe Afenifẹrẹ (AG) pelu awọn enia mẹrinlelogun kan ro wipe nwọn ko awọn nkan ija jọ lati gbe ogun ti awọn olotu Ijọba apapọṣe ki nwọn si bi nwọn lulẹ, ni on niran wipe Dokita Kwame Nkrumah, alakoso Ijọba ilu awọn Aganyin ni Ghana fun on ni ẹdẹgbarin pọnun (£7,000) pe ki on na fun ikede irẹpọ larin ilu enia dudu ni ilẹ Afirika.

O ni nigbati Dokita Nkrumah na fun on ni owo na, ko sọ wipe dandan gbọn ọna bayi bayi ni ki on ha a si, sugbọn on alara ni on ha a kakiri fun awọn oṣelu ti on ri wipe o yẹ lati ha a fun.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Ajalolon'eru, Iro Ni Pepe Npa : Yekinni Ojikutu Ni Nwon Ko Yo On Lolori Alapata Rara

EKO – Jamba s'ole, onile taji! Irohin ti a tun gbọ lẹhinti iwe irohin wa ti ose ti o kọja ti jade nipa ọrọ awọn ẹgbẹ Alapata eran l'Eko ati gbogbo agbegbe'rẹ nipa ọrọ olori ẹgbẹ wọn, Oloye Abudu Yẹkini Ojikutu, ti nwọn sọ wipe awọn ti gbe oye olori kuro lọdọ rẹ; a gbọ wipe eleyi kiṣe otitọ rara. Oloye Ojikutu si ni olori awọn ẹgbẹ alapata na.

Ayiluka "Eleti-Ọfẹ" ti o tẹsẹ bọ ṣokoto lati wa idi bi ọrọ ti o di koko na tin ni ntotọ ni awọn kan ti a darukọ ninu irohin wa ti ọsẹ ti o kọja ya lọ kuro ninu ẹgbẹ na. Nwọn si ti nfa ọrọ na mọ ara lọwọ ti pẹ, sugbọn awọn ooye enia ti o wa ninu ẹgbẹ na lẹhin Oloye Yẹkini Ojikutu ni nwọn wa.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ti nwọn duro gbọin-gbọin lẹhin Oloye Ojikutu ni ija lo de ni orin di owe, baba ẹgbẹ awọn ko ṣẹ awọn rara. Nwọn ni gbogbo eyi ti o de yi ọrọ ote ni. Nwọn ni o tilẹ yẹ ki awọn gbagbe ẹṣẹ kẹṣẹ ti Balogun Eko yi ba fi ṣẹ awọn, ki awọn niran gbogbo ọdun isoro ti o ti nko awọn jẹ bọ.



Balogun Ekọ

B A RACHEL NI :

## Suru Ni Oro Ilorin Pelu Igbomina

Ẹ jọwọ, ẹ gba mi laye ninu iwe irohin lati da esi pada fun arakunrin kan ti o pe ara rẹ ni Ọdẹkunle ninu iwe Irohin Imọlẹ ti ọse yi, ti o ni isọkusọ ni "Olofintoto" yin sọ nipa ọrọ awa ọmọ Igbomina, Ọffa mo Ekiti pẹlu awọn ara Ilọrin lori ọrọ ki a yan Ijọba Ipinlẹ fun wa.

Mo ro wipe ọmọ ilewe ni Ọgbẹni Ọdẹkunle ti o kọ iwe na nitoripe gbogbo nkan ti mo ri ti mo si ka ti Olofintoto yin sọ, otitọ ọrọ ni o sọ. Nitotọ ọrọ awa ọmọ Igbomina pẹlu ara Ilọrin ti di suru.

Awọn ọmọ Ilọrin paapa mọ wipe ọmọ atata ni wa ori ọrọ rogbodiyan ti ipinlẹ na nitoripe ko tilẹ rẹ wa rara lati ọdun pupọ ti a ti raba ọrọ na boyi. Nkan ti o yẹ ki ọkunrin wa, Ọgbẹni Ọdẹkunle sọ ni pe ki o kan saara si "Olofintoto" yi nitoripe on ni o jẹ ki a mọ ibiti nwọn ba ọrọ na de ni Kaduna ati ni gbogbo agbegbe ilu wa.

Lati igba ti OLOFINTOTO yi ti bo awọn loju eguu, ti o ti jẹ ki a mọ gbogbo bi nkan ti nlọ si, emi ti mo nkọ iwe yi ti gbọ bi awọn ọmọ Igbomina mọ Ọffa ti ngbadura fun un. Nitotọ Olotitọ ilu ni oṣika ilu ni oju awọn enia buruku ọmọ araiye. O ṣe pupọ ti ko ra awo jẹ fun wa.

Mo ro wipe Ọdẹkunle ti o pe "Olofintoto" ni Ọlọtẹ ti de ile ti pe ati pe ko si mọ bi nkan ti nlọ si lọdọ awọn oṣelu wa ni aiye ti a wa yi. Ọrọ ọmọde ni gbogbo alaye ti o nsọ sinu iwe Irohin Imọlẹ. Awa agbalagba ti a wa ninu ẹgbẹ ọmọ Igbominaparapọ mọ ibiti bata ti nta wa lẹsẹ.

Ẹ ṣe pupọ fun aye ti ẹ gba mi,
Olotu iwaju ni ẹo ma lọ.

Emi ni,
Jekọbu Baba Rachel

**Akiyesi** A dupẹ lọwọ rẹ pupọ Ọgbẹni Jekọbu fun alaye ọrọ rẹ; awa paapa mọ wipe ti a ba sọ fun Olofintoto wa wipe ki o fesi si ọrọ Ọgbẹni Ọdẹkunle nkan a ba jẹ patapata. Boya alaye Olofintoto wa ni ko yẹ e, sugbọn ọkawe wa kan ti o njẹ Iyeru-Ọkin ọmọ Ọlọfamọjọ ti tun sọ pato ti o mbẹ ninu ọrọ na. O ni Ọrọ awọn pẹlu ara Ilọrin kiṣe ọrọ ija rara, o si ti kin Olofintoto wa lẹhin fun wahala rẹ ti ṣe lori ọrọ wa. Eleyi na ti to ni tiwa.

**Ọlotu**

## Won Yo Awon Kan Ni Ile Iwe

NSUKKA—Awọn Alakoso ile iwe giga ti nwọn npe ni University of Nigeria ti awọn ti nkọ ẹkọ nibẹ ṣe alaigbọnran laipe yi ti yọ awọn enia mejidinlogun nile iwe-giga na patapata.

Ọga ile iwe na, Dokita Johnson si ṣe ikede fun awọn yoku wipe awọn ti ṣe tan lati gba wọn pada ti nwọn ba le kọ iwe tituba pe awọn ko ni hu iru iwa buruku bayi mọ, ati pe awọn yio ma gbọran si awọn tiṣa awọn lẹnu.



Aworan yi ni ti Ọlọla Julian Amery, Minisita alamojuto ọkọ ofurufu ni ilu Gẹsi. Ọlọla na jẹ eniti o fẹran irin ajo pupọ. Ọmọ ọdun metalelogoji si ni, o si fẹran a nkọwe fun awọn oniwe irohin.

## OMO ALAKE Junnu Larin Ilu

ABẸOKUTA— Enmọ wọ ilu, ọmọ Ọba Alake Ademọla Keji ti jẹ Adenrele ti nwọ ...ọe ni iyawo fun Ọlọ... Odutọla, Ọgbẹni ... a ni Ijẹbu Ode ni a gbọ wipe nwọn ti nwa lati nkan bi ọjọ merindinlogbọn ti nwọn ko mọ ibiti o gbe gba lọ.

N... ti a gbọ ni pe lọjọ ti n...n fẹ ọmọbinrin abileko na ku, o ba nwọn njẹun alẹ tan ninu agbala baba rẹ ti ongbe. Nigbati ilẹ mọ lọjọ keji ni nwọn fẹẹ ku. Nwọn fi lọgun, awọn fi lọgbọn nwọn ko ti mọ ibiti ọmọbinrin na wa di igbati a nkọ irohin yi.

Eni ọdun mejilelogoji ni obinrin na, iṣẹ agbẹbi ọmọ (Nursing Sister) ni o nṣe ni Ijẹmọ ni Abẹokuta lati igbati o ti ti ilu Oyinbo de.

## Omo Awosika Paapa Sonu

Irohin ti o tun jẹ a gbọ yanu ti a tun gbọ ni ti ọmọ Oloye F. O. Awosika ti nwọn npe ni Olusọla ti o wa wo awọn obi rẹ lati ilu Oyinbo ti nwọn ni o sọnu larin Ọtta si Abẹokuta lati nkan bi ọsẹ keji.

Lati ọjọ ti awọn obi ọmọ na ko ti ri ni nwọn ko le sun ti nwọn ko le wo. Gbogbo igbo ọna Abẹokuta ni nwọn nwo kiri tọsan to'ru pẹlu ireti pe boya awọn le ṣe alaba pade rẹ.

Bẹna ni irohin ti abiyami kan ara Ilesha ti o njẹ Ọmọlade Alaba ti a gbọ wipe o junu, nwọn nwa kiri. O fi ọmọ ti o ntọ lọwọ sile ni ile ọkọ rẹ ni Oke Ilọrọ ni Ilesha lati bi ijẹsan ti ọkọ rẹ ti nṣe gbajare Kiri.

# Kabiyesi Oba Alake Aeemola Keji (11)

## (Lati Owo Omo Abati)

### Ileiwe Baptist

Laiṣe iyemeji gbogbo ẹnyin ọkawe itan mi l o r i Ọba Alake Ademọla Keji ni ẹ ti gbọ bi aseyẹ iwuye tabi igbade si lori Ọba na ti dun to lọjọ ti nwọn fi jẹ ọba ni ojude Ọba ni Ake ni ilu Abẹokuta ni iwọn ọdun mejilelogoji nisisiyi.

Lẹhinti ọba yi ti gun ori oye tan, o wa mura o nlọ si Ṣọṣi ijọ kọkan ni ọsẹ ọjọ meje meje ti o fi yi gbogbo ile isin ti nwọn jẹ pataki pataki ni i l u Abẹokuta kakiri tan fun adura wipe ki on le ma lo aṣẹ-ida ti nwọn gbe fun on na daradara, ki on si ma j'ọla pẹlu i b ẹ r u ọkan lori awọn enia on na.

Ni iwọn nkan bi ọdun mejilelogoji sẹhin ile iwe-giga kan ni o wa f u n gbogbo awọn ọmọkunrin ni ilu Abẹokuta ; ile iwe giga na ni eyiti awọn ilu Abẹokuta da silẹ ti nwọn npe ni Abẹokuta District Grammar School ni Igbein.

Alaikosi ile iwe g i g a fun awọn ọmọkunrin n i ilu ilu Ẹgba to ba yi jẹ ki awọn Oyinbo o j i ṣ ẹ Ọlọrun ti nwọn npe n i American Baptist Mission bẹrẹ si kọ ile iwe-giga kan fun awọn ọmọkunrin nibi kan ti nwọn npe ni Oke Egunya ni Agọ-Owu ni ọdun 1920, ọdun keji lẹhinna ni nwọn to pari kikọ ile iwe na, nwọn si npe e ni Baptist B o y s' High School.

### Idi-Arabọ

Ẹniọwọ Alufa (Rev.) S. G. Pinnock ti iṣe alakoso ile-iwe giga na ṣe wahala pupọ pẹlu iyawo rẹ ki nwọn to le yori si kọ ile na tan. Ọpọlọpọ enia pataki pataki ni nwọn si ti kọ ẹkọ ninu ile iwe giga na ni Abẹokuta ati awọn ọmọ miran ti awọn obi wọn ran wa sibẹ lati idalẹ.

Ṣiṣi ile iwe yi jẹ nkan kan pataki ti Alaiyeluwa Ọba Ademọla Keji kọ ṣe nigbati o gun ori itẹ.

Awọn Oyinbo o j i ṣ ẹ Ọlọrun American Baptist Mission na ni nwọn tẹ ẹnikinni ti o kọ ni ile-iwe ẹkọ fun awọn ọmọbinrin ni igboro ilu Abẹokuta

(Woyoku loju ewe kẹfa )

# Ibadan L'awa T'agbe N'jaiye

## (Lati Owo "Olofintoto)

Mo ti lọ ṣe abẹwọ awọn enia mi ni Ibadan ni ile Oluyọle pẹ diẹ; ki a tilẹ sọ gasikia, nko ti lọ ju ẹkan lọ nigbati ofin pajawiri ti de ba wọn ni Ipinlẹ Iwọ Orun na, ṣugbọn eyiti mọ lọ ni aipẹ yi jẹ ki nniran orin kan ti awọn onilu wa ma nkọ fun wa pẹlu awọn ẹgbẹ mi nigbati mo wa ni ilu na.

Onilu wa Ayantọla, a ma kọrin wipe, "Ni Ibadan ni a wa ti a gbe njaiye, ti a gbe njẹ iyan. Awa ko mọ wipe ebi npa ọmọ ẹnikọkan." Ẹnyin ọrẹ mi, ọrọ ti kuro ni ọrọ "a ko mọ wipe ebi npa ọmọ ẹnikọkan mọ nisisiyi. Ilu Ibadan ti aiye ode isisiyi ti yatọ pupọ pẹlu awọn enia inu rẹ.

Nigbati mo de Ibadan ti mo lọ si ile ibiṣẹ a w ọ n akọwe Ijọba ni Oke Agodi, mo ri wipe ọ p ọ l ọ p ọ awọn akọwe o n i - k ọ l a ti mo ri, ti mo si ti fi silẹ ni ẹ n u i ṣ ẹ ni igba ti lo. Boya iwọ ti o nka iwe mi k o m ọ nkan ti nwọn npe ni "igba"-igba ẹ s u n w o n a ( austerity measure ) n i awọn a r a Ib a d a n sọ ni Ọsitẹriti, ti awọn obinrin wọn ko ri owo mu lọ si ọ j a fun nkan ọbẹ mọ.

### Sobu Tuntun

M ori ṣọbu orisisiṣi ti awọn enia-dudu ati Oyinbo kọ si' Gbagi ati opopo Amunigun. Nwọn ni ko nṣe wipe awọn ṣẹṣẹ ri owo fi kọ awọn ṣọbu na; awọn ti tu owo ti awọn fẹ fi kọ wọn jọ sile tipẹ, ki "igba" ọsitẹriti to de.

A n t i Abada Alatẹ ni Amunigun sọ fun mi wipe asiko ọsitẹrti na ko si ẹniti k o m ọ-ati o l o w o ati bọkinni ilu ni o b a wi.

Anti Abada ni ọ d u n Keresimesi lo mbọ yi awọn ko ti mọ bi awọn yio ti ṣe ta, gbogbo ọja ti awọn fi owo olowo ko jọ ni o kunle jaburata ninu ṣọbu awọn.

Awo-yanu ni ṣọbu tuntun t i awọn Oyinbo aladapọ ṣẹṣẹ ṣi si Gbagi, ko si nkan ti o fẹ ra ti o ko ni ri nibẹ. O ... ẹrẹ lati abẹrẹ ti a fi nran aṣọ de mọto-ayọkẹlẹ. Ẹja tutu ni tabi ẹran malu titi o fi de ẹran ẹlẹdẹ. Isọ ẹja-tutu paapa wa lọtọ nibẹ.

Mo gbọ wipe l ọ j ọ ti nwọn ṣi ṣ ọ b u tuntun na awọn ara Ibadan lọkunrin ati lobinrin dabira nibẹ. Ọba Olubadan Akinyẹle ni o ba wọn gba adura si i o si sọrọ ti o ba eti mu fun awọn oniṣẹowo wa wipe otitọ lo dara pupọju.

### Apata Ganga

Ọpọlọpọ awọn o ṣ i ṣ ẹ lọkunrin ati lobinrin n i awọn Ọ g a adopọṣẹ-iṣẹ (Corporation) da sile nitoripe owo ko si pupọ tobẹ mọ. Awọn ti o nrọ omi ọpẹ oyinbo sinu agolo ni ọrẹ na ba wi pupọ a t i awọn ti nwọn nfi ike ṣe oriṣiṣi nkan.

Ọpọlọpọ awọn Olonjẹ wọn si ti ko igba sile.

### Okuta Wolu

M o b a ọpọlọpọ awọn obinrin ti nwọn nta aṣọ ni Gbagi s ọ r ọ lori ọja wọn. Nwọn ni wọn ko mọ nkan ti o r ọ l u ilu Ibadan lọdun ni. Nwọn ni lati bi nkan bi o ṣ u mẹfa w a t i rogbodiyan ti de ba a w ọ n oṣelu n okuta ti wọlu, nwọn ni awọn ko mọ nkan ti awọn le ṣe si ti okuta na.

Awọn kan ni awọn gbọ wipe ọrọ okuta na kiṣe ti

(Woyoku lojn ewe kẹfa)

HAVE YOU
exchanged your
OLD WEST
AFRICAN COINS
for Nigerian
Money ?
FREE EXCHANGE
at banks ends on
December 31st,
1962.

## Ayiluka

Kan Oju abe ni ko Fun Awon ALAPATA ERAN. E ka Oro re loju ewe karun.

# ELETI—OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABELS & TELGERAM

28 Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI—ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 468 Phone 23370

VOL. XIV No. 846, SATURDAY, NOV. 23, - NOV. 30, 1962


# Ewu Moto

A ki iaju ẹni silẹ ki talubọ ki o ko wọ Awa onirohiu Eleti—Ọfẹ a tun fẹ tẹ mọ ẹnyin ti o nkawe wa leti wipe jamba tabi e u agbako mọto ti o nṣẹlẹ lojojumẹ ni ilẹ wa kiṣe ẹjọ awọn Olotu Ijọba wa bikoṣe ti awa paapa.

Ẹlẹjọ ki mọ ẹjọ rẹ lẹbi ki o pẹ ni ilunlẹ ni ọrọ wa na. O ni a gbọ wipe moto ja si Kanga ọla a gbọ wipe motọ bẹ si Koto, o pa enia mejila. Ti a ba wa idi rẹ lọ ti a ba tun wa a bọ, a o ri wipe ẹjọ awa-moto ni

Ninu ki o mọ ni iwe-ẹri awọn ti o nwa mọto lọwọ, ninu ki o ti mu ọti a-mu-para tabi ki o ti bẹna si ewe taba "igbo" ni kọrọ.

Ni ilu Aganyin, awọn alaṣẹ ilu ibẹ ti gbe ofin jade fun awọn awa-mọto wipe ẹnikẹni ti o ba mu ọti a-mu-para ti o ba wa mọta ẹwọn ọdun mẹdogun ni awọn yio ju oluwarẹ si. Eleyi ni awọn tiwa nfi ṣe ayọ lojojumọ lọdọ awọn ọlọpa.

A bẹ ẹnyin oselu wa, ki ẹ mọ iru Ofin ti ẹ o gbe jade lori awọn ti o nwa mọto ni iwakuwa.

## Awon Omode

A mọ nkankan daju, iyẹn ni pe ko si ofin kofin ti le se lori ọrọ yi, a fi ti awọn ọlọpa wa ti o nṣe eto lori wọn oninọto paapa ba kaju ọkanjuwa wọn, ti nwọn gba owo abẹtẹlẹlọwọ awọ awamọto, ti wọn si duro gbagba lati mu ofin ṣẹ.

Lẹhin eyi o yẹ ki awọn obi paapa kọ awọn ọmọ wọn wipe ki nwọn ma ṣe pẹlẹpẹlẹ loju mọto. Oju titi mọto kiṣe ile ere ti a ngba bọlu afẹsẹ-gba.




**Iwọ ha lè gbe iyawo bi? Iwọ le ṣe bẹ laipẹ lọ titi bi o ba bẹrẹ lati ma f'owo pamọ ni ọdọ Barclays nisiyi!**

Latigba degba ni ki o ma f'owo pamọ, ki o si toju rẹ s'ile ipamọ owo. Fi ọkàn tán Barclays nipa itọju owo rẹ, eyiti iwo yio si gbà pada yio si ju iye ti o fiibẹ lọ! *Lọ bère* ni banki ti Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo rẹ pamọ. Awọn ni yio fun ọ ni imọràn ati iranlọwọ to darajulọ.

"IGBEYAV





# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

LATI ỌWỌ AYILUKA

## Ojikutu

Awọn Yoruba ni "ẹniti ko ba mọ wẹ ki bọ sodo," iyẹn ni ọrọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ ALAPATA ẸRAN ti nwọn ni awọn rọ Oloye Abudu Yẹkini Ojikutu loye Olori awọn ati pe ki o ko gbogbo iwe ẹgbẹ awọn pẹlu nkan miran ti o ba jẹ nkan awọn wa fun baba-ẹgbẹ tuntun ti awọn ṣẹṣẹ yan, Ọgbẹni Lawani Madojutọla.

Ọrọ na ru emi Ayiluka loju pupọ, mo ni ki nmọ ṣee ni ọrọ ẹniti ko mọ iwẹ ti o ja s'odo, ṣugbọn mo wa mọ nkankan daju. Mo mọ iwọn nkan bi ọdun kẹdọgbọn (1937) sẹhin ti Oloye Yẹkini Ojikutu ti nko awọn alapata ẹran yi jẹ nigbati nwọn wa ni ọja Ereko atijọ ti o si nṣe agbọrọdun fun gbogbo wọn titi de Yaba mọ Agege.

## Minisifa

Mo ni ran igbati Oyinbo kan ti a npe ni C. Martins nṣe akọwe ile Igbimọ Minisifa ilu Eko, bi ọrọ kan ba ti fẹ di koko nipa awọn alapata ẹran l'Eko, Oloye Ojikutu a ti gbe ẹwu rẹ lati lọ kan oju abẹ ni iko lọdọ awọn awọn oni ilu na.

Bi o ti wu ki awọn alapata ẹran yi jẹ alai—more to ko tilẹ yẹ ki nwọn gbagbe igba ogun (Great War) nla ti awọn alaṣẹ Ijọba fi ijanu si owo ẹran tita lọja (Meat Control), ti ọ jẹ ogun ajaku akata ni ọrọ awọn alapata ẹran, bi ẹnikan ninu awọn alapata yi ba ri ọmọde ti o wọ kaba ti o fẹ ra ẹran, nwọn a fo iganna, nwọn a fi isọ silẹ. Oloye Ojikutu yi na lo dide si gbogbo rẹ ti ọrọ na fi dẹrọ fun awọn alapata ẹran.

## Igba Ote

Mo gbọ wipe eleyi ki ṣe igba kinni ti awọn yio kọ di ọtẹ si Olori wọn yi pe awọn ko fẹ mọ. Nigba aiye Ọgbẹni Salami Ladọtun beni awọn kan ya lọ pẹlu awọn Ologbe B.B Salami ati Madojutọla pẹlu awọn bebe. Asẹhinwa, asẹhinbọ nwọn tun wa tuba ni. Ko si nkan ti le, ti ki rọ.

Boya awọn alapata yi tun fẹ fi oye kun Oye Ọgbẹni wa na ni. Ti nwọn ba fe ṣee ki nwọn maṣe gbagbe wipe Oloye Abudu Yẹkinni Ojikutu na ti jẹ oye Basọrun fun awọn ara adugbo Oluwọle, o na si ni B.I gun gbogbo Imale Eko, Balogun ara ilu Eko, olori awọn ọmọ ẹgbẹ Ọbanibaṣiri, igbakeji baba ẹgbẹ awọn ọmọ ile iwe giga King's College, on na si tun ni olori awọn ẹgbẹ Ẹlẹja ti Ijọba Apapọse da silẹ.

Oloye Ojikutu, emi Ayiluka nki nyin o! Itoju Eko di ọwọ yin, Alhaji Masha ọmọ yin ni Oluwọle sa ti de ori aga Igbimọ Minisifa. Ki e si ba mi ki awọn aburo yin, awọn bi Alhaji Lasisi Ojikutu, Fasasi Ojikutu ati Alhaja Abiba iyawo Kofo ni Ebute-Mẹtta. Ki nwọn ma gbagbe ike ẹran temi ki nri nkan fi ṣe Sunday lọla.

Iyoku di ọsẹ ti mbọ.

## Balewa

Mo gbọ wipe alakoso Ijọba wa, Alhaji Tafawa Balewa npalẹmọ lati tun yan awọn olubadamọran miran. Mo gbọ wipe o fẹ gbe iṣẹ le Alhaji Mattama Sule ati Dokita K. O. Mbadiwe lọwọ. Nkan ti o fa a ti Ọgbẹni wa na ṣe tun fe yan awọn olubadamọran na ko ye mi si, ṣugbọn mo ro pe ọrọ Minisita Alhaji Usman Sarki ti o ṣẹṣẹ lọ jẹ Ọba awọn Tapa ni ilu Bida lo fa a.

Mo ki alakoso wa na pe o ku ipalẹmọ o, bi oye minisifa ba ṣẹku, ki o ba mi wa ipo Minisifa alamojuto e'o ile owo ki nle ṣe igba keji Oloye Okotie-Eboh. Ọrọ owo kiṣe yẹyẹ rara.

## Omo Alake

Enmọ, iru ewo niyi ? Abilekọ sọnu larin ile ! ọrọ na ya mi lẹnu ; a gbọ ju igba silẹ ni irohin ti ọmọ Ọba Alake. Iya'fin Adenrele aya Oloye Odutọla ti Ijẹbu-Ode ti a gbọ wipe o junu, nwọn nwa a lati bi ọjọ mẹrinlelogun sẹhin.

Mo mọ Adenrele bi ẹniti o mọ owo, Iya-abiye ni mo ma npe e nitoripe iṣẹ agbẹbi (Nucsing Sister) ni o nṣe ni Ake l'Abẹokuta, ẹni dudu ni, o si ri rubutu.

Ẹnyin gbọmọ-gbọmọ, ẹ jọwọ ẹ ba Alake wa ọmọ rẹ o ati ọmọ Awoṣike ti o tun sọnu. Ọmọ ẹni i ku o daraju ọmọẹni sọnu lọ.


## National Bank of Nigeria Limited.

CHRISTMAS SHILLING FUND—DECEMBER, 1962.

Depositors in the Christmas Shilling Fund are hereby reminded that in accordance with the regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Monday, 3rd December 1962.

Withdrawals can only be made by the depositor in person and on production of his pass book. In the case of distant depositors, early application for a withdrawal form should be made to the Manager of the Branch concerned, such application to be accompanied by the depositor's pass book, for interest to be entered up.

Withdrawals for the year will close on the 31s December 1962, and depositors who fail to withdraw on that day cannot do so until next Christmas.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the depositor's surnames on the date shown hereunder and the depositors who fail to apply on the prescribed date shall not be attended to until Monday, 10th December 1962.

| | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | A | Monday | 3rd | December | 1962, |
| B | TO | H | Tuesday | 4th | ,, | ,, |
| I | ,, | N | Wednesday | 5th | ,, | ,, |
| | | O | Thursday | 6th | ,, | ,, |
| P | ,, | Z | Friday | 7th | ,, | ,, |
| A | & | O | Saturday | 8th | ,, | ,, |

For the year 1963, deposits will be taken as from Wednesday, 2nd January, 1963.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER

# Oba Alake

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Ni Agọ Ijaiye ni Ologbe iya alanu, Iya-afin G. C. Lumbley gbe ngbe pelu ọkọ rẹ. Alufa Lumbley ti o si nwọ ojule kan de ojule keji ti o nko awọn ọmọbinrin jọ lati kọ wọn lẹkọ lai gba owo; Iya'fin Lumbley si pe ile ẹkọ rẹ na ni Baptist Girls' School. Eleyi si ni ile ẹkọ kinni fun awọn ọmọbinrin ni Abẹokuta.

Nigbati aye ko to fun awọn ọmọbinrin ti nwọn nwa si ile ẹkọ na Ologbe Iyafin Lumbley kọwe si ilu Amẹrika wipe ki awọn alanu Oyinbo ran on lọwọ nit ripe on fẹ kọ ile ẹkọ giga fun awọn obinrin ilu Ẹgba. Nitotọ nwọn ran Oyinbo na lọwọ, o si wa ilẹ ra si ibi kan ti nwọn npe ni Idi-Aba leti ile ologbe Iya-afin Subuọla ọmọ Ẹgbẹrongbe ti mo fẹnu kan itan rẹ laipẹ yi ninu iwe iran mi.

Awoṣanu ni ile-ẹkọ na nigbati nwọn kọ ọ tan, nwọn si ṣi i ni ọjọ keji oṣu October ninu ọdun 1924 (2nd October 1924). Gomina ti nwọn npe ni Sir Hugh Clifford ni o wa lati Eko wa ṣi ile ẹkọ Baptist Girls' High School na ni Idi-Aba. Oba wa Ademọla keji yi si wa ninu awọn ọba ti nwọn ba wọn wa si ibi iṣile na.

# Owo olopa teoyinbo oloko ti o gb'owo

EDINBURGH—Awọn Ọlọpa ilu Oyinbo mba Oyinbo ọlọkọ oju omi kan ti orukọ rẹ njẹ Philip Bauer, ẹni adọta ọdun, ro ẹjọ ole lọwọ; nwọn ni o ji ẹgbawa pọnun (£20,000) owo kọrẹnsi atijọ gbe ti nwọn ni ki o ba awọn fi ọkọ ko wa si ilẹ enia-dudu nigba kan.

Nigbati nwọn mu ọkunrin na de iwaju Adajọ kọtunla, Bauer ni on ko jẹbi rara. Agbẹjọro awọn Ọlọpa si ṣe alaye fun adajọ bi ọrọ na tiri. O ni o to ogun ọdun si asiko yi ti nwọn ko awọn owo kọrẹnsi (West African Currency notes) si inu ọkọ ọkunrin yi ti nwọn npe ni Nevada Keji pe ki o ba awọn ko nwọn wa si ilẹ enia-dudu.

Ọkọ na ko lọ jinna pupọ ki o to tan si agbami okun. Nigbati o pẹ nwọn yọ ọkọ na, nwọn si ko awọn nkan ti o wa ninu rẹ, nibẹ ni awọn apoti ti nwọn di owo yi si wa.

Ọkunrin yi si ko owo na o gba ọdọ awọn Oyinbo ti mba wọn parọ owo lọ nilu ti nwọn npe ni Zurich pe ki nwọn ba on parọ owo na. Lẹhinti nwọn parọ wọn tan ni nwọn gbọ wipe nwọn ko gba owo na mọ rara.

# Awon China Gbe Ogun Ti Ilu India

NEW DELHI — Awọn ara ilu China ti gbe ogun gbigbo na kan ti awọn mejeji npe ni ti nwọn. O un na gbona pupọ to bẹgẹ ti awọn orilẹ ode ti nwọn npe ni China na ko ọpọlọpọ ogunlọgọ ọmọ ogun (ṣoja) wọn lọ si eti ilu kan ti nwọn npe ni Bomidila, nwọn si gba ilu na.

Ni ọjọ Tuesday ni Ọgbẹni Nehru Alakoso ilu India lọ kunrin ati lobinrin si idi Radio lati sọ fun gbogbo awo nilu India lọkunrin ati lobinrin pe awọn ara ilu China ti gbe ogun ti awọn, awọn si ni lati ba awọn ja ija na de opin ni

Ọgbẹni Nehru ni o da on loju gbangba wipe awọn ni awọn yio bori ogun na, awọn ko si ni gba ẹbẹ ti awon ba bẹrẹsi ṣe ti awọn.

## Awon Jaguda Gbe Awon Alapata Lowo

APAPA— Ni alẹ ijẹfa ni awọn ogboju ole kan gbe ogun-a-daja lọ ba awọn Hausa ti o nta malu ni agọ ti nwọn ngbe ni Apapa, ti nwọn si gba gbogbo owo ọwọ wọn patapata, nwọn si tun lu wọn ni alubolẹ, eleyi ko si jẹki awọn gbogbo alapata Eko roju raye lati pa ẹran

A gbọ wipe ni irọlẹ ọjọ na bi awọn Hausa ẹleran ti o nta ẹran malu ti ta ẹran wọn tan ti nwọn pada sile wọn ni awọn ọlọṣa na gbe moto de pelu ibọn, olukuluku mu gbogbo ọwọ wọn ti nwọn pa lọjọ na wa

Alhaji Kala, Ọka ninu awọn Hausa na ti o fẹ ṣe bi ọkunrin ni nwọn yin ibọn si lọrun. Gbogbo owo ti awọn ole na ri gbe lọ jẹ nkan bi ẹgbẹdẹgbọn pọnun (£5,000).

# Ibadan L'awa T'agbe Njaiye

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Ibadan nikan, awọn ara Eko fi ara gba ninu rẹ. Nwọn ni awọn gbọ wipe nitori eyi awọn obinrin alaṣọ ni oju-gọta Ereko ni lati ṣe etutu jaburata.

Baba agbẹ kan ara Odoọna ti o wa ra nkan, ti mo ba pade ni Gbagi sọ fun mi wipe bi koko (cocoa) awọn yio ti ta si lọdun ni Ijọba ko ti fi ye awọn rara, sugbọn ko da on loju bi nkan na le dun yungba-yungba bi ti atijọ.

## Awon Woli

Agbẹ yi ni ni aiye atijọ bi ọdun Keresimesi ba ti ku bi oṣu meji ni awọn agbẹ ti nma ko ere oko wa silẹ, ṣugbọn ọrọ ko ri bẹ mọ nisisiyi

Mo de ile-isin awọn Aladura ati Serafu ni Agbokojo, Oke Fọkọ, Isalẹ Ijẹbu, Ibukọ ati Ori-Eru mọ Oke Ọfa, gbogbo awọn ariran ati woli lọkunrin ati lobinrin ni awọn na nkun sinu fun bi gbogbo nkan ti nlọ si ni ode nisisiyi ni Ipinlẹ Iwọ Orun. Awọn na ko ri ba ti ṣe mọ.

Mo gbọ wipe gbogbo awọn ijọ Serafu ati Kerubu pẹlu awọn ijọ Ṣọṣi Aladura ti ṣe ipinu lati ṣe ipade gbogbogboo fun adura akanṣe ki ilu le toro, ki aiye ko roju.

Ibadan ni mo wa ti mo gbe njaiye.

# BBC Has Largest Gramophone Library

LONDON — So rich and varied are the contents of BBC's gramophone library, built up over forty years of broadcasting, that a distinguished musician o n c e likened it to "an oriental 'warehouse'". It has to be, in order to feed the vast frontier of entertainment represented by many different kinds of programmes broadcast in the BBC's domestic and overseas services. It contains over half a million commercial r e c o r d s and some 7,000 historical 'archive' records, of which 75 per cent have no known matrix.

One, a n d sometimes three or more copies of every record issued in Britain are purchased by the BBC gramophone library. There are 700 different makes, and thousands of prefixes a n d numbers. Any record can be l o c a t e d within forty seconds by means of a huge card catalogue showing some 600,000 titles, 3:0,056 composers and nearly 45,270 artists. There are, for instance, 66 different recordings of Schubert's 'Unfinished Symphony', 73 recordings of Beethoven's 5th Symphony, and 315 of the 'Blue Danube'. About 11,000 records are lent out to BBC producers each month.

Highly prized records in the archive collection include: Marie Tempest singing 'The Jewel of Asia', in her part of Mimosa San, from 'The Geisha'–a 7-inch Berliner; Edna May-the original 'Belle o New York'-singing 'The Purity Brigade' from the show, a record made in 1903 1900; and Victor Maurel singing Hahn's 'L'Heure Exquise', a record made in Paris in 1903 and valued at £100. Non-musical 'museum' records include speeches by Robert Browning, Stalin, Lenin, the Emperor Franz Josef, Puccini, C a r m e n Sylva (Queen of Rumania), King Alfonso of Spain, and Rudolph Valentino.


# The advanced quality of the Fiat "sixes"

## FIAT 2300 and FIAT 1800 B

more power, elegance, comfort, disc brakes



The Fiat 2300

PRICES

| | 2300 Ex Lagos | 2300 Ex Turin | 1800 B Ex Lagos | 1800 B Ex Turin |
|---|---|---|---|---|
| STANDARD SALOON | £1,380 | £698 | £1,250 | £618 |
| STATION WAGON | £1,530 | £775 | £1,380 | £710 |
| SPECIAL SEDAN | £1,780 | £845 | —— | —— |

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (E.B.) IBADAN KANO KADUNA JOS PORT HACOURT ABA



**Read And Advertise In Eleti-Ofe News Paper**

# Ijoba Ni Enikeni Ko Gbodo Se Ipade L'Eko Mo

Awọn Olotu Ijọba Apapọṣe ti gbe ofin kan jade lori ana wipe awọn ko gbọdọ ri ki enik ẹni pejọ pọ ni ita tabi ki nwọn tọwọ larin ilu Eko fun oṣu meji. Nwọn ṣe alaye ninu Iwe ofin na pe enikẹni ti o ba fẹ ṣe ipade ni lati kọwe si ile iṣẹ Minisita alamojuto aṭo ilu tabi Ọga awọn Ọlọpa lati gba iwe-aṣẹ.

Awọn enia pataki ninu ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NC NC) ti te ọkọ leti lọ si Ẹnugu fun ipade pajawiri kan. Olelu kan ṣe ẹnu foro sọ fun wa wipe ipade o iji na fẹrano lati mọ nkan ti awọn yio ṣe nipa gbo-gbo rike-rudo ti o wa lode nisisiyi ti awọn ba de ipade awọn asoju Igbimo aṣofin ti nwọn fẹ ṣe l'Eko ninu oṣu ti mọọ yi.

Awọn kan ni nipa ọrọ Oloye S.L. Akintọla ti o fẹ pada si ipo Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibadan ni nwọn fẹ lọ sọ ni Ẹnugu na.

# Adajo So Oga Olopa Kan Sewon

Adajọ Kotu kan sọ ọga Ọlọpa kan ti o nje David Fashọyin sẹwọn oṣu mẹsan lori ẹjọ iyederu iwe awamoto ti o tako fun ọ n mọto ti nwọn ba a ro.

Adajọ na tun fi awọn ọmolehin rẹ, awọn Christopher Idu ati Bamide Agbonzie ti nwọn jọ n ṣe iṣẹ bruku na sẹwọn oṣu mẹsan mẹsan pẹlu rẹ. O ni wọn ti sọ ọrọ iwe aiyederu na di iṣẹ patapata.

# Dokita Maja

(O bere loju ewe kini)

Dokita Maja ni on fun Ọgbẹni J.S. Tarka ni ẹgbaa pọnun (£2,000) ninu owo na, o ni on na ẹgbẹrun pọnun (£1,000) fun Mallam Ibrahim Imam, olori awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Hausa kan. O ni on tun ra mọto ayọkẹlẹ meji fun Ọgbẹni Tarka ninu owo na.

Dokita Maja ni lẹhin eyi, on da ẹgbẹ awọn ọdọ kan silẹ ni Nigeria ti on sọ ni Express Youth Club nigbati awọn Ọgbẹni Imam ati Tarka ti sọ wipe awọn ko le tun da ẹgbẹ oṣelu tuntun miran sile mọ, o ni on si ni awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ na kakiri ni Eko, Abẹokuta ati Ibadan.

Dokita Maja ni on niran wipe awọn Ọgbẹni Amuwo, Sumbọ Jibowu, Onitiri, Badmus, Shashore ati awọn miran ti awọn jọ wa ni itimọle sọ fun on wipe Oyinbo ọlọpa kan ti nwọn npe ni Coleman bẹrẹsi fi ibọn ati ọbẹ dẹruba awọn wipe ki wọn ko jẹwọ tipa tipa, o tilẹ gboju gboya, o tẹ Amuwo ni nkan ọmọkunrin re ti ko le tọ. O ni a fi igbati on gba ni imọran wipe ki o lọ ri dokita.

Nwọn si nro ẹjọ na lọwọ di igba ti a nko irohin yi lọwọ.



PHILIPS (NIGERIA) LTD.
78 R.P.M. at 7/- each.
P 82463 H
Bonuc-ni/Nkeyere
wofur Nkeyere Me E.K.'s Band
P 82470 H
E. Asaa & His guitar Band 45 RPM 6/9d
P 382492 Fat
Gbin Aj.../Orin Alatele
Joseph Ogunbele & His group P 382480 F
Kwoto Attack/Merenu
Agedez The Comats
P 382315 F
Nmo Nnipa Nymas
Ada Monni Amurasi
E.K.'s Band.
PHILIPS
of course...
the [illegible] of the century

# Awon Asoju Igbimo Ilu Ceylon fi Aga Fo ara Won Lori

CEYLON—Ni owurọ ana ni a gbọ wipe awọn aṣoju ti nwọn yan si ile igbimọ awọn aṣofin ni ilu Ceylon fi aga fọ ara wọn lori ninu ile Igbimọ na nigbati nwọn nṣe ipade lọwọ.

Nwọn ni ijọngbọn na bẹ silẹ nigbati Alaga na kọ jalẹ lati fi ẹnu kan ọrọ owo ẹhin ti awọn ẹgbẹ alatako ilu na ni awọn alakoso Ijọba ilu na ngba, awọn si fẹ ki nwọn fi ofin si i.

Ija na pọ tobẹgẹ ti o fi jẹ wipe awọn Ọlọpa ni nwọn wa ko gbogbo wọn kuro nibẹ.

Eka oro Ayiluka ni oju ewe karun fun oro awon Alapata eran ilu Eko ati awon nkan miran.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 2?370 EDITOR (OLOTU) OLA ONATADE
15, Kosoko Street, Lagos.